# AWKA JOURNAL OF ENGLISH LANGUAGE AND LITERARY STUDIES

# (AJELLS)

**Volume 11 Number 1**
**July, 2024**

# Èèwọ̀ Yorùbá Nínú Ètò Ìṣèlú Ilẹ̀ Nàìjíríà
# (Èèwọ̀ (Taboo) Yorùbá in Political Happenings of Nigeria)

**Dayọ̀ Àkànmú**
Department of Nigerian Languages Education
College of Languages and Communication Arts Education
Lagos State University of Education Ọ̀tọ̀/Ìjànikin
Noforija Campus, Ẹ̀pẹ́ P.M.B 007 Festac Town, Lagos Nigeria
dayoakanmu2002@yahoo.com

**Àṣamọ̀**
Èèwọ̀ jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àṣà Yorùbá tí ó dàbí òfin tí ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ rú, tí àwọn ọmọ Káàárọ̀-o-ò-jíire ń ṣe àmúlò rẹ̀ láti ìgbà ìwáṣẹ̀ fún ààbò àti àlàáfíà tó péye láàrin ìlú. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹ̀sìn àjèjì, ọ̀làjú àti ohun ìgbàlódé kò jẹ́ kí ọ̀pọ̀lọpọ̀ èèwọ̀ Yorùbá fi ẹsẹ̀ múlẹ̀ ní àwùjọ òde òní, síbẹ̀síbẹ̀ àwọn ọmọ Yorùbá tí èdè àti àṣà Yorùbá yé yékéyéké sì nígbàgbọ́ pé lóòrè-kóòrè ni èèwọ̀ ń farahàn nínú ètò Ìṣèlú àti Ìṣèjọba orílẹ̀ èdè Nàìjíríà èyí tí kò mú àlàáfíà bá ìlú. Détà fún iṣẹ́ yii wá láti inú ọ̀kan-ò-jọ̀kan àṣàyàn ìwé tí ọ̀rọ̀ èèwọ̀ àti ìṣẹ̀lẹ̀ ìṣèlú ṣodo sínú wọn pẹ̀lú ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò onígbẹ̀fẹ́ láti ọ̀dọ̀ àwọn abẹ́nà ìwádìí méjì tí ó mọ tìfun-tẹ̀dọ̀ èèwọ̀ ilẹ̀ Yorùbá. Ète ìtúpalẹ̀ a-jẹ-máṣà àti àwùjọ ni a lò fún ìtúpalẹ̀ bébà yìí nítorí pé nínú àṣà àwùjọ ni èèwọ̀ wà àti pé àwùjọ ni ó ń ṣe àmúlò rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe farahàn nínú ìṣẹ̀lẹ̀ ètò ìṣèlú àtẹ̀yìnwá ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà. Ìyànjú láti jẹ́ kí á mọ ohun tí èèwọ̀ jẹ́, bí ó ṣe bẹ̀rẹ̀, àwọn ohun tó farahàn gẹ́gẹ́ bí èèwọ̀ nínú Ìṣèlú Ilẹ̀ Nàìjíríà, dídẹ́jàá èèwọ̀ àti ìjìyà tí ó wà fún ẹni tó dẹ́jàá èèwọ̀ pẹ̀lú èròǹgbà pé, ó yẹ kí àwùjọ òde òní ṣe àmúlò ìjì̀yà tó tọ́ fún dídẹ́jàá èèwọ̀ bí ó ṣe wà ní àtètèkọ́ṣe láìfi ọ̀pọ̀lọpọ̀ àkókò ṣòfò tàbí ki ọwọ́ òṣèlú bọ ì̀wà ọ̀daràn kí ìdájọ́ òdodo tó wáyé bí ti òde òní, ni ó ṣokùnfà pépà yìí. Ìmújáde èrò inú pépà yìí fi ìdí ọ̀rọ̀ múlẹ̀ pé èèwọ̀ gan-an ni ó di òfin tí àwùjọ ń ṣàmúlò lóde òní, tí dídẹ́jàá rẹ̀ túmọ̀ sí rírú òfin èyi tí ó yẹ kó ní ìjìyà lábẹ́ òfin. Ó hàn gbangba pé lóòótọ́ ni ìjìyà wà fún arúfin nínú èèwọ̀ láìfi àkókò ṣòfò, ṣùgbọ́n lóde òní, nígbà mìíràn, arúfin kì í tètè gba ìdájọ́ ẹ̀ṣẹ̀ tàbí kí ó má tilẹ̀ jìyà ẹ̀ṣẹ̀ rárá nítorí pé àwọn aláṣẹ

lè ti fi ọwọ́ òṣèlú bọ̀ ọ́. Ó yẹ kí àwọn aláṣẹ ìlú àti àwùjọ lápapọ̀ padà sí ẹsẹ ààrọ̀ kí á sì ṣe àwòkọ́ṣe àwọn ọ̀na tí Yorùbá ń gbà láyé ọjọ́sí láti ṣe ìdájọ́ òdodo èyí tí kìí fi àkókò ṣòfò tàbí gbọ́mọ Ọbà fún Ọ̀ṣun lórí adẹ́jàá tàbí arúfin èèwọ̀

**Kókó ọ̀rọ̀:** Èèwọ̀ Yorùbá, Ètò Ìṣèlú, Òfin, Dídẹ́jàá, Àwùjọ

## Abstract

Èèwọ̀ (taboo) is one of the inestimable elements of the Yoruba culture comparable to the present time laws of the nation, culturally established to comply with, and avoid its violation. It has always been employed for maintenance of peace and tranquillity in Yoruba society from time immemorial. In spite of modernity, dominance of foreign religions over its traditional counterpart, which seemed to have been responsible for suppression of some vital taboos in contemporary Yoruba society; It is against this background that the paper observes that taboo always manifests and violated upon in the political happenings of Nigeria in a way that creates injustice, instability and chaotic situation. Data were collected from the primary and secondary sources and were analysed using cultural and social method of analysis. This is because taboo is a product of society and it is utilized by the society as evident in the earlier socio-political happenings of Nigeria. Efforts to establish what taboo is, its origin and instances of taboo in the political occurrences of Nigeria, its violation and appropriate punishment for offenders, with a view to establishing justification for this cultural phenomenon which devoid of injustice and unwarranted delay of justice as against what plays out presently in our contemporary justice system is the focus of this paper. Findings reveal that taboo metamorphoses into what is known as laws today, while lack of respect for it is tantamount to violation that must be appropriately sanctioned under the law. Finding from the study also reveals that indeed, in traditional setting, appropriate and instant judgment is given to the violator of taboo without unnecessary delay of justice or politicisation of justice, as can be seen in the justice system of our contemporary

society. Government and the society at large should go back to the basis and emulate methods adopted by our forefathers in adjudicating disputes and effectively given appropriate judgement on violation of taboos without compromise and delay of justice.
**Keywords:** Yoruba taboo, Politics, Law, Violation, Society

## Ìfáàrà

Káríayé ni èèwò jé. Òun ni àwọn Gèésì ń pè ní tàbùú (tàbóò). Ó férẹ má sìí àwùjọ tí kò káárà-máásìkí ọ̀rọ̀ èèwọ̀ bí ó ti wù kí ó mọ. Lára àṣà àti ìṣe àwọn Yorùbá ní èèwọ̀ ti jáde, ó sì jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn èròjà tí wọ́n fi ń ṣe àkóso ìlú tí ìlú fi ń rójú ráyè. Ìmọ̀ àyíká àti àkíyèsí àdúgbò àwọn ẹ̀yà Yorùbá ní ó bí èèwọ̀. Àwọn àgbàlagbà ìlú bíi olórí ẹlésìn tàbí ìbọ kan, àwọn ọba ìlú, àwọn ìjòyè, àwọn baálẹ̀ àti àwọn baálè ilé ní ó dúró gẹ́gẹ́ bí agbátẹrù èèwọ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá. Àwọn wọ̀nyìí gan-an ní ó máa ń fi èèwọ̀ kọ́ àwọn ọmọ lẹ́yìn wọn tí wọn kìí fi tàpá sí tàbí dẹ́jàá èèwọ̀.

Ní ìgbà láíláí, ohun tí àwọn àgbà bá ti pè ní èèwọ̀ ti di ohun àìgbọ́dọ̀ṣe. "Ìwòrì kìí ru ẹ̀kú, eégún kò gbọ́dọ̀ ná bábaláwo tó bá gbọ́fá yanran yanran lóòtù Ifẹ̀". Òfin ní ọ̀rọ̀ èèwọ̀, èèwọ̀-di-òfin ní ọ̀rọ̀ èèwọ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, ẹnìkan kìí sì rú u. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé èèyàn tó bá pa èèwọ̀ mọ́ ní èèwọ̀ ń gbè, ṣùgbọ́n ẹni tí ó bá dẹ́jàá tàbí kọ etí ọ̀gbọnìn ṣébọ ní èèwọ̀ máa ń dá lẹ́jọ́, èèwọ̀ á máa gbèjà ara rẹ̀. Èèyàn tó bá ṣe ohun tí ẹnìkan kò ṣe rí, ojú onítọ̀hún á rí ohun tí ẹnìkan kò rí rí. Báyìí ní ojú rí nígbà náà tí a fi ń jobì lọ́jà Ẹdẹ, tí ohun gbogbo ṣe ń lọ létò letò.

Lóde òní, Èsúó tí pàdí dà ó ti ń lé ajá kiri. Àwọn èèyàn tí tasẹ̀ àgẹ̀rẹ̀, wọ́n ti tàpá sí àwọn èèwọ̀ tí a jogún lọ́dọ̀ àwọn bàbá wa tí wọ́n fi ń ṣe àkóso ìlú, tí ohun gbogbo fi ń rọ̀ṣọ̀mù. Ìwà ọ̀làjú nínú èyí tí àsà mọ̀-ọ́n-kọ mọ̀-ọ́n-kà tí jẹ̀ jáde àti àyọjúràn àwọn ẹsìn òkèèrè tí a gba wèrè rẹ̀, tí kò jẹ́ kí àṣà àti ìṣe wa jọ wá lójú mọ́ ni kò jẹ́ kí á má ní èèwọ̀ mọ́ nínú ohun gbogbo tí à ń ṣe lóde òní. Bẹ́ẹ̀ ẹ̀fọ́ kìí lé ẹ̀fọ́ láwo ní wọ́n wí. Abájọ tí olórin ìbílè kan ṣe sọ pé:

"Ẹ jónífá ó bọfá

Ẹ jọ́lọ̀ṣun ó bọ̀ṣun
Ẹ jólódù ó bodù
Káyé lè gún

Èyí já sí pé pípolongo ẹ̀sìn àtọ̀húnrìnwá láti dìmẹ́ẹ́rí àṣà èèwọ̀ pẹ̀lú àwọn oríṣìí nǹkan mèremère láti fa ojú àwọn Yorùbá mọ́ra kò jẹ́ kí ó fi ìdí múlẹ̀ bí ó ti yẹ mọ́. Ipò tí àwọn ọmọ Yorùbá tí ó ń ṣe ìjọba lóde òní wà kò gbè wọ́n tó ti àwọn tí ó ń ṣe àkóṣo ìlú ní ayé àtijọ́ nítorí pé ọ̀pọ̀ nínú wọn ní alákọ̀wé; èyí kò sì jẹ́ kí wọ́n kọ ibi ara sí àwọn èèwọ̀ tí ó yẹ kí wọ́n máa wò mó lóde òní. Ohun tí ó ṣe okùnfà pépà yìí gan-an rè é.

## Ìtumọ̀ Èèwọ̀

Ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn onímọ̀ ní ó fún 'èèwọ̀' ní oríṣii ìtumọ̀ káàkiri àgbáálá ayé, ara wọn ní Crystal (1997) tí ó pe èèwọ̀ ní 'tàbúù' nínú ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé:

> "The word 'taboo' has been borrowed from Tongan, where it means 'holy' or 'untouchable'. Taboo exists in all known cultures, referring to certain acts, objects; or relationship which society wishes to avoid".

Ohun tí Crystal (1997) ń gbìyànjú láti sọ ní èdè Gẹ̀ẹ́sì ni pé:

> A yá ọ̀rọ̀ tí à ń pè ní 'tàbú' láti inú èdè Tongan ní ati pé, ìtumọ̀ rẹ̀ ní 'ohun mímọ́' tàbí 'ohun àìgbọ́dọ̀ fọwọ́ kan. Tàbú wá láti inú gbogbo àṣà àwùjọ tí a mọ̀ tí ó ní ṣe pẹ̀lú àwọn isé kan, ohùn kan tàbí àjọsepò kan tí àwọn ènìyàn àwùjọ kìí fẹ́ mẹ́nubà.

Ọláọ̀ba (2001) kò fi béè yàtọ̀ sí èrò ti Crystal. Òun náà sọ ní èdè Gẹ̀ẹ́sì pé:

> "The word "taboo" has "èèwọ̀" as its translation and it means forbidden things. For example, it is a taboo to disturb officers of the law by noise-making or coughing"

Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni èdè Yorùbá ni pé:

> Èèwọ̀ ní à ń pè ní 'tàbú', ìtumọ̀ rẹ̀ sì ni 'ohun tí kò wọ̀' tàbí 'ohun tí a kò gbọ́dọ̀ ṣe'. Bí àpẹẹrẹ, èèwọ̀ ni

kí á fi ariwo dí àwọn alákòóso tàbí agbátẹrù òfin lọ́wọ́ nílé ẹjọ́.

Táíwò, (1986) rí èèwọ̀ gẹ́gẹ́ bí ìyànjú láarín àwọn Yorùbá láti kọ́ àrọ́mọdọ́mọ wọn ní àwọn nǹkan tí àṣà tàbí ìgbàgbọ́ wọn kò gbà láàyè.

Ní àárín àwọn ọmọ Oòduà, bí ó ti wù kí ọ̀rọ̀ kan pakásọ̀ tó, kò lè ṣe kí ó má ní ìtumọ̀, kódà àdìtú gan an ní ìtumọ̀. Àwọn ọ̀rọ̀ mìíràn wà tí sípẹ́lì wọn àti pípè wọn jẹ́ bákan náà ṣùgbọ́n tí ìtumọ̀ wọn yàtọ̀. Bí àpẹẹrẹ "dẹ̀pẹ̀" jẹ́ ọ̀rọ̀ tí a máa ń lò fún ẹni tí ó gọ̀ nílẹ̀ Yorùbá ṣùgbọ́n ní orílẹ̀ èdè Benin ní Kotonú tàbí láàrin àwọn Ègùn, ẹni tí ó bá gbọ́n tàbí tí órí rẹ̀ pé ní wọ́n ń lò ó fún.

Fún ìdí èyí, a lè sọ pé orísìí ìtumọ̀ ní a lè fún èèwọ̀ ní ibìkíbi ti ìtumọ̀ rẹ̀ bá ti bá òfin gírámà mú àti àyíká ibi tí a ti lò ó. Ọlájubù (1975), sọ pé "è" àkọ́kọ́ nínú "èyí" àti "è" kejì náà "èyí" ní wọ́n papọ̀ pè ní – èyíkéyìí tí kò "dára" tàbí tí kò "wọ̀" tàbí tí kò sunwọ̀n láti hù ní ìwà ní wọn papọ̀ tí wọ́n ń pè ní "èèwọ̀".

Gẹ́gẹ́ bí àlàyé ìyá Ẹfúnṣègbè àti bàbá Mọgbà (Oníṣẹ̀ṣe àti àgbà ọdẹ ni Ògbómọ̀ṣọ́), ohun àìgbọdọ̀ ṣe "Èrìwọ̀" ní a sọ di èèwọ̀ àti pé, bí ìgbà tí a bá gbé àwọn lẹ́tà kan mì nínú ọ̀rọ̀ ni gẹ́gẹ́ bí ó ṣe farahàn nínú pípe àwọn orúkọ Yorùbá bíi:

Àyántáyọ̀ tí ó di Àńtáyọ̀
Ọláníkẹ̀ẹ́ tí ó di Làńkẹ́ẹ̀
Ọláoyè tí ó di Lóoyè
Ọláọ̀ré tí ó di Lọ́ọ̀rẹ́

Bọ́lárìnwá àti Ajayéọba (2021) kò sàìtanilólobó pé ohun tí ó jẹ́ èèwọ̀ ti di àìgbọdọ̀ṣe nígbà tí wọ́n ń ṣàlàyé nípa àwọn èèwọ̀ tó jẹ mọ́ àwùjọ lọ́balọ́ba èyí tí àwọn ọba kò gbọdọ̀ kọ etí ọ̀gbọn-ìn sí ní gbogbo ilẹ̀ Yorùbá. Ọládìran (2020) náà jẹ́ kó yé wa pé ohun tí kò

wọ̀, tí Yorùbá ń pè ní èèwọ̀ dàbí òfin tí ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ rú nígbà tí ó ń sọ̀rọ̀ nípa bí Orò ṣe jẹ́ èèwọ̀ fún obìnrin láti fojú kan nílùú Ògbọ́mọ̀ṣọ́. Lára àwọn onímọ̀ tí ó fara mọ́ èèwọ̀ gẹ́gẹ́ bí ohun tí kò wọ̀ tàbí ohun àìgbọdọ̀ ṣe ni: Àjàyí (2022: 68), Àgòrò (2021:173), Ọlátúnjí (2021:10), Adélẹ́yẹ (2020:42), Ajíbádé (2020), Akíntán (2020:1), Adéoyè (1978:41), Bọ́lájí Ìdòwú (1996:52), Adéwọyin (2009:21), Mike (2004:31) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ní àkótán, a lè sọ pé ìyànjú láti se ètò lámèyítọ́ ní àwùjọ àwọn Yorùbá ní ó ṣe okùnfà òfin fún ìkóraẹni-ní-ìjánu. Irú ẹni tí ó bá sì tẹ òfin báyìí lójú ní à ń sọ pé ó ṣe ohun àìgbọdọ̀ṣe, tí a mọ̀ sí èèwọ̀. Ẹni tí ó bá rú òfin ní àwọn ìjọba ń fììyá jẹ nípa owó sísan sínú kòtò ọba tàbí kí wọ́n fi sínú túbú ṣùgbón ẹni tí ó bá dẹ́jàá èèwọ̀ ní òrìṣà tàbí ẹ̀mí àìrí ń wá egbò dẹ́kun fún, ìyẹn ni pé èèwọ̀ ti gbèjà ara rẹ̀.

Pẹ̀lú gbogbo atótónu tí a ti ń bá bọ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ yìí, a lè sọ pé èèwọ̀ jẹ́:

> Àtọwọ́dá ohun tí a gbà pé àìgbọdọ̀ṣe ni pẹ̀lú àṣẹ kàn-án-pá gẹ́gẹ́ bí òfin àdáyébá láti fi kọ́ ìran Yorùbá láti màjèsín títí di àgbà gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ àti ìgbàgbọ́ wọn láti yẹ ara fún ohun tí a ò fẹ́ ṣe tàbí láti fi kó ara ẹni ní ìjánu ohun tí a lérò pé kò tọ́nà.

## Bí Èèwọ̀ Ṣe Bẹ̀rẹ̀

Òkun kìí gùn kí ó má ní ibi àmúwá rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú pé, oríṣìí ọ̀nà ní Yorùbá ń gbà, láti ṣe ètò lámèyítọ́ ní àárín àwùjọ. Ọ̀kan lára ọ̀nà bẹ́ẹ̀ ni ṣíṣẹ̀dá òfin àti èèwọ̀ fún ìkóra-ẹni-ní-ìjánu àti ìpamọ́ irú òfin àti èèwọ̀ bẹ́ẹ̀ jẹ́ àdáyébá láti ọ̀dọ̀ àwọn àgbà. Èyí ní ó fà á tí Yorùbá fi ń sọ pé “Àgbà níí bá ni í ṣèlú, ọmọdé ní í bá ni í ṣe ilé ẹni”. Láìdéènà pẹnu, a lè sọ pé èèwọ̀ ti wà láti ìgbà tí ìwà ti ṣẹ̀.

Lóde òní, ọ̀pọ̀ èèyàn ní wọ́n rò pé ẹ̀tàn lásán ní èèwọ̀ jẹ́. Ohun tí ó fa èyí ni pé ó nira fún ènìyàn tí kìí ṣe àgbà ọ̀jẹ̀ nínú ìmọ̀-èèwọ̀ láti lè sọ pàtó ibi tí egbò èèwọ̀ ti ṣẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí Ìdòwú (1996:125) ṣe sọ, àwọn Yorùbá máa ń ru ẹ̀sìn wọn kiri ibikíbi tí wọ́n bá ń lọ̀ ní àti pé,

gbogbo àwọn èsìn yìí ló jẹ mọ́ òrìṣà kan tàbí òmíràn. Nípa bíbu ọlá fún àti yíyẹ́ àwọn òrìṣà yìí sí fún mímọ́ gẹ́gẹ́ bí alárinà Olódùmarè tàbí láti sá fún ìbínú wọn, èyí tí ó lè da làásìgbò sílẹ̀ ní àwọn èèwọ̀ nípa òrìṣà ṣe wáyé. Èyí gán-an ni ó fà á tí àwọn Yorùbá ṣe máa ń sọ pé "Èèwọ̀ òrìṣà". Lọ́rọ̀ kan sá, a lè sọ pé nínú ẹ̀sìn, tí ó kó ìwà àti ìṣe Yorùbá pọ̀ ní orírun èèwọ̀ wà pẹ̀lú ẹ̀kọ́ pàtàkì tí wọ́n fẹ́ láti fi kọ́ ènìyàn.

Àkíyèsí tún fi hàn pé ní àwùjọ àwọn Yorùbá, ipò àwọn ọba, ìjòyè, àwòrò òrìṣà àti àwọn babaláwo ṣe pàtàkì púpọ̀ nítorí ọlá, iyì àti àyẹ́sí pẹ̀lú ìtẹríba tí àwọn ènìyàn ń fún wọn. Ohun tí ó ṣe okùnfà èyí ni pé, yàtọ̀ sí wí pé wọ́n jẹ́ àkàndá Olódùmarè gẹ́gẹ́ bí ẹmẹ̀wà àti aṣojú, orísìí nǹkan ní ó tún rọ̀ mọ́ ipò wọn. Lára ohun tí ó ń sọ wọ́n di ẹni àpésìn ní nípa ìmọ̀, ibi àti wíwọ orísìí ọ̀pọ̀lọpọ̀ èèwọ̀ láti lè mú irú ipò bẹ́ẹ̀ nìyí gẹ́gẹ́ bí a ti dá a mọ̀ wọn láti òkè wá. Abájọ tí ọ̀kan lára àwọn abẹ́nà iṣẹ́ ìwadìí yìí (Àgbà ọdẹ) ṣe sọ pé "ní gbàrà tí wọ́n bá ti fi ọba jẹ ní ó ti di ẹni ọ̀wọ̀ torí pé oríṣìí àwọn ìṣéra àti èèwọ̀ ni ó yí i ká láti mú ipò rẹ̀ àti òun gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó wà ní ipò náà di ẹni mímọ́.

Àwọn èèwọ̀ mìíràn tún wà láti inú ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ẹ̀yà tàbí orílẹ̀ kan, èyí á sì máa hàn nínú oríkì wọn ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú oríkì àwọn ìdílé Olú-Òjè.

Òjé kìí j'ẹ̀gà
K'ẹ́ni má m'óròrẹ́

Èyí fi hàn pé èèwọ̀ ní fún ọmọ tí ó bá jáde láti inú ìdílé yìí kí ó jẹ́ ẹyẹ ẹ̀gà.

Ní ọ̀nà tí agbára, pàápàá jùlọ nípa àwọn egbò igi (oògùn) ní ilẹ̀ Yorùbá, tí a bá rí ẹni tí ó ń sa ògidì oògùn tí ewé sì ń jẹ́ fún olúwarẹ̀, ó di dandan kí onítọ̀hún máa wọ oríṣìí èèwọ̀ tí yóò jẹ mọ́ ìṣéra àti òpòlọpọ̀ àmúmọra. Oògùn sísà yìí jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àṣà àti ìṣe Yorùbá; tí ó sì tún bá ẹ̀sìn wa lọ. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, nípa wíwá ààbò àti ìṣẹ́gun lórí ọ̀tà, a lè sọ pé oògùn sísà náà jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú orírun àwọn èèwọ̀ ilẹ̀ Yorùbá nítorí pé ẹ̀mi àìrí àti àwọn àǹjọ̀nnú ní oògùn ń bá ṣiṣẹ́.

**Ẹ̀já Dídá**

Níwọ̀n ìgbà tí ìfohùnsọ̀kan ti wà pé ohùnkóhun tí kò bá wọ̀ ní èèwọ̀ àti pé ohun tí a kò gbọ́dọ̀ ṣe tàbí dánwò ni. Àwọn Yorùbá gbà pé bí èniyàn bá dán irú ohun bẹ́ẹ̀ wò, olúwarẹ̀ yóò dan tán. Ẹnìkẹ́ni tí ó bá wá dán irú ohun báyìí wò ni à sọ pé ó dá ẹ̀já èèwọ̀. Ẹni tí ó bá ṣé ohun tí ẹnìkan kò ṣe rí, ojú rẹ̀ yóò ri ohun tí ẹnìkan kò rí rí. Ìgbàgbọ́ Yorùbá ní pé, ohùn enìyàn ní ohùn Ọlọ́run. Bí ènìyàn bá dẹ́jàá láarín àwùjọ, dandan ni kí o jìyà. Irú ìjìyà yìí pín sí ọ̀nà mẹ́ta: yálà láti ọ̀dọ̀ ènìyàn ní, tàbí òrìṣà tàbí kí ó jẹ́ láti ọ̀dọ̀ Olódùmarè.

Ìjìyà tí ó máa ń ti ọwọ́ ènìyàn wá ni èyí tí a rí nínú kí ọba kan jẹ láti ìdílé olóyè kí ó sì kú sórí oyè tàbí kí ó máà ní ojú oórì ní ààfin yàtọ̀ sí àwọn tí ó bá jẹ́ alágbára tí wọ́n máa ń fi ẹ̀wọ̀n gòkè tàbí wọlẹ́. Irú ìdílé báyìí ní àwọn ènìyàn máa ń ṣe àtakò rẹ̀. Wọn kò ní jẹ́ kí irú ìdílé bẹ́ẹ̀ jẹ ọba nínú ìlú mọ́. Èkejì ni pé tí a bá ní èèwọ̀ ni fún ènìyàn láti ja olè tàbí kí ó má fi ọwọ́ gbe òjò tí onítọ̀ún wá dán an wò; ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé ààrá láti ọ̀dọ̀ ọbakòso (Ṣàngó) ni yóò sán pa olúwarẹ̀ tàbí kí ó ṣe é bí ọsẹ ṣe ń ṣe ojú. Ní ti ìjìyà láti ọ̀dọ̀ Olódùmarè, tí a bá sọ pé ènìyàn kò gbọ́dọ̀ da ilẹ̀ ọ̀rẹ́ tàbí tí alájọbí lẹ́yìn tí wọ́n bá ti mulẹ̀, tí ènìyàn bá wá dá irú ẹ̀já bẹ́ẹ̀ àyọrísí rẹ̀ kìí sunwọ̀n rárá, wéréwéré ní ohun abẹ́nú yóò máa yọ́ olúwarẹ̀ ṣe títí tí àṣírí yóò fi tú síta. Irú àkókò yìí ní wọ́n ń sọ pé èèwọ̀ gbèjà ara rẹ̀".

À bá mò kí a má ṣe é, a ṣé tán ó wá di aápọn ní ọ̀rọ̀ èèwọ̀ jẹ́. Ìgbẹ̀yìn èèwọ̀ sí adẹ́jàá, tí èèwọ̀ bá gbèjà ara rẹ̀ tán, kìí sunwọ̀n. Ó máa ń ta bá igbá ta bá àwo ni. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn èèwọ̀ yìí ní wọ́n dúró gẹ́gẹ́ bí kókó àtẹ́lè fún ìhùwà ní àwùjọ Yorùbá èyí tí àwọn baba ńlá wa sọ di ohun ẹ̀tọ́ tí kò ní àbàwọ́n rárá. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá sì ni pé ọ̀dọ̀ Olódùmarè, àwọn atẹ̀wọ̀rọ̀ àti àwọn babańlá wa ní àwọn èèwọ̀ yìí ti ṣẹ̀ wá. Ẹnìkẹ́ni tí ó bá sì ti ṣe ohun tí ó lòdì sí àwọn èèwọ̀ bẹ́ẹ̀ ti hu ìwà tí ó burú jáì, tí kò tọ́, tí kò sì yẹ ọmọlúàbí. Fún ìdí èyí, ìjìyà tí ó tọ́ sí adẹ́jàá gbọ́dọ̀ tí ọ̀dọ̀ àwọn ẹ̀dá nínú àwùjọ wà tàbí òrìṣà (ẹ̀mí àìrí) àti Olódùmarè gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà láti fi ìdí òdodo hàn. Irú ìdájọ́ báyìí ní Yorùbá máa ń ní ìgbàgbọ́ nínú rẹ̀. Ìdí nìyí tí àwọn

Yorùbá ṣe ń pe Olódùmarè ní “A dákẹ́-dájọ́” àti “A-ṣè-kan-mákù”. Èèwọ̀ gbèjà ni èyí.

Irú ìdájọ́ bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ àìsàn (ìgbóná) tàbí ikú. Èyí sì lè kó bá ọ̀pọ̀ ènìyàn. A jẹ́ pé 'yóò bá ọ', kìí ṣe ìwọ nìkan ni yóò bá mọ́. Yóò wá di pé “tí ará ilé ẹni bá ń jẹ kòkòrò, tí a kò bá tètè dá a lẹ́kun hẹ̀rẹ̀huru rẹ̀ kò ní jẹ́ kí á sùn lóru”.

**Èèwọ̀ Nínú Ìṣèjọba Ilẹ̀ Nàìjíríà**

Tí a bá ń sọ nípa èèwọ̀ nínú ìṣèjọba ilẹ̀ wa, kò gbọ́dọ̀ jẹ́ àkókò yìí nìkan tàbí ìjọba àwarawa nìkan ní à ń sọ nípa rẹ̀. Ó ní láti bẹ̀rẹ̀ láti ìgbà òmìnira tí a ti gba ìjọba ní ọdún 1960 nínú èyí tí àwọn ọmọ Yorùbá kó ipa ribiribi nínú rẹ̀. Ẹwẹ̀, tí a bá tún sọ nípa ìṣèjọba ilẹ̀ wa, a ó ma sọ̀rọ̀ nípa ìṣèjọba ní ìjọba ìbílẹ̀, ìpínlẹ̀ àti ti ìjọba àpapọ̀. Kò sí ibi tí àwọn ọmọ Oòduà kò ti kópa nínú àwọn ọ̀nà ìṣèjọba mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí a mẹ́nubà yìí. Ibìkíbi tí ọmọ Yorùbá bá sì wà, a kò lè kóyán èèwọ̀ ilẹ̀ Yorùbá kéré níbẹ̀.

Bí a kò bá gbàgbé, a ti sọ níwájú pé, ohun tí kò wọ̀, tí kò sunwọ̀n àti ohun àìgbọdọ̀ ṣe ní èèwọ̀ jẹ́ àti pé èèwọ̀ ní ó bí òfin; ó sì wà lára àwọn èròjà tí a fi ń to ìlú. Ìjìyà kò sàìsí fún ẹni tí ó bá dẹ́jàá èèwọ̀ tàbí rú òfin yálà láti ọ̀dọ̀ ènìyàn (ìjọba) tàbí láti ọwọ́ Olódùmarè. Lára irú àwọn èèwọ̀ tí ó di òfin náà ní: ìwọ kò gbọ́dọ́ dálẹ̀ ènìyàn, ìwọ kò gbọ́dọ̀ pa ènìyàn, ìwọ kò gbọ́dọ̀ jalè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọ̀nà wo wá ni irú àwọn nǹkan wọ̀nyí ń gbà ṣẹlẹ̀ láàrin àwọn ọmọ Oòduà nínú ètò ìṣèjọba ilẹ̀ wa? Irú ìjìyà wo ni àwọn arúfin tàbí adẹ́jàá ọmọ Yorùbá ń gbà? Àkóbá wo ni àwọn ìwà yìí ń ṣe fún ilẹ̀ wa? Àwọn nǹkan wọ̀nyí ni a gbé yẹ̀wò lábẹ́ ìsọ̀rí yìí.

Láìfi àkókò ṣòfò, ọmọ Yorùbá ní Awólọ́wọ̀ àti Akíntọ́lá tí wọ́n ṣe gudugudu méje àti yààyà mẹ́fà nínú àwọn ikọ̀ tí ó jà ìjàgbara fún òmìnira orílẹ̀ èdè yìí. Àwọn akọni ọmọ Yorùbá méjèèjì yìí ní ìtàn òṣèlú fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ tẹ́lẹ̀ wí pé ọ̀rẹ́ ìmùlẹ̀ niwọ́n títí tí ó fi di ọdún 1962 sí 1965 nígbà tí ìwà ọ̀dàlẹ̀ láarín àwọn méjèèjì sọ ọ̀rẹ́ ìmùlẹ̀ wọn di ọ̀rẹ́ ìdìtẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àkíyèsí wa. A ti fi ìdí èyí múlẹ̀ tẹ́lẹ̀ wí pé

èèwọ̀ ni kí ènìyàn dálẹ́ ara wọn ṣùgbọ́n a kò lè sọ pàtó wí pé ẹnìkan ní ó dálẹ́ ẹnìkejì láàrin àwọn méjéèjì. Agbọ́n ń ṣe, ìkamùdù ń ṣẹ; ojú olóko sì rè é, kọ̀lọ̀bọ̀-kọlọbọ ní ó wú. Àwọn tí ó fara mọ́ S.L Akíntọ́lá ní Olóògbé Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ ní ó dálẹ̀ ọ̀rẹ́ ẹ̀; òun ni ó fẹ́ lọ du ipò gíga mìíràn ní ìjọba àpapọ̀ tí ó sọ fún Akíntọ́lá pé kí ó máa delé de òun gẹ́gẹ́ bí alákòóso (Premier) ìwọ̀ oòrùn àti pé, òun yóò gba ipò òun padà gẹ́gẹ́ bíi alákòóso (premier) tí ọwọ́ òun kò bá tẹ ipò tí òun ń wá lọ sí ìjọba àpapọ̀ l'Ékòó mọ́. Lóòótọ́, ọ̀rọ̀ ò wọ̀ mọ́, Awólọ́wọ̀ fẹ́ padà sí orí àlééfà rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àdéhùn wọn ní Akíntọ́lá bá fi ààké kọ́rí. Èyí gan an ní ó fa ọ̀rọ̀ tí àwọn ènìyàn fi ń dápàárá nígbà náà wí pé "Akíntọ́lá takú". Akíntọ́lá takú nítorí pé ó rí ìwà ọ̀rẹ́ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí "anìkànjọpọ́n" àti "onímọtaraẹni nìkan".

Bákan náà ní ó jẹ́ pé àwọn tí ó nígbàgbọ́ nínú Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ rí S.L Akíntọ́lá gẹ́gẹ́ bí ọ̀dàlẹ̀ ènìyàn tí ó lẹ̀di àpò pọ̀ pẹ̀lú àwọn Gàmbàrí tó wà níjọba àpapọ̀, nígbà náà nítorí pé ó gbé ní àárín wọn fún ìgbà pípẹ́. Èyí gan-an ni ó ṣokùnfà ọ̀rọ̀ tí olóyè Bọ́lá Ìgè, ọ̀kan lára ọmọlẹ́yìn Awólọ́wọ̀ sọ wí pé:

> Àwọn ààrò mẹ́ta tí wọ́n wà nídìí ìbàjẹ́ jíjẹ ìwọ̀ oòrùn níyà ni Bàléwà, Sardauna àti Olóyè S.L Akíntọ́lá, ẹni tó tún ṣẹ̀ṣẹ̀ di ẹ̀ẹ̀kẹtàlá Ààrẹ-ọ̀nà-kakanfò. Tọba–tìjòyè ló wá ń wó Akíntọ́lá bíi ẹni tí ìgbẹ̀yin-ìn rẹ̀ kò níí dára pàápàá jùlọ nígbà tí ó tún lọ̀ọ́ jẹ oyè tí ìgbàgbọ́ wà pé a ti fi ré torí pé àwọn tó jẹ Ààrẹ ònà kakanfò ṣaájú rẹ̀ kò ṣe rere. Ó dà bí ẹni pé ẹ̀yìn-in Látòósà ní a fi oyè náà ré. Kò sì sí nǹkan mìíràn táà bá fi pe ẹni tí ó joyè náà ṣáájú Akíntọ́lá ju orúkọ ẹni náà lọ - ABURÚMÁKÙÚ. (Ọdeajo, 1997:44)

Àwọn ìbéèrè tí a ṣe nínú ìsọ̀ òkè yìí ni pé: Njẹ́ òtítọ́ ni pé ìgbẹ̀yìn Akíntọ́lá kò dára nítorí ọ̀nà tí ó gbà kú? Ṣé a lè sọ pé Akíntọ́lá dẹ́jàá èèwọ̀ nípa ilẹ̀ dídà? Èèwọ̀ wo ni ó wà nínú kí a jẹ oyè Ààrẹ-ọ̀nà kakanfò? Ohun tí a lè sọ sí àwọn ìbéèrè yìí ni pé, ó ṣòro láti sọ pé ìgbẹ̀yìn olóògbé S.L Akíntọ́lá kò dára látàrí bí ó ṣe kú nítorí pé kìí ṣe òun nìkan ni ó kú ní ọ̀nà yìí. Lára àwọn tí ó kú ní Sàdáúnà, Bàléwà àti Okotiebọ wà àti pé nígbàkúùgbà tí ológun bá gba ìjọba

ẹnikẹ́ni ní ó lè lọ sí. Bí kò bá ṣe pé olóògbé Ọbáfémi Awólọ́wọ̀ náà wà ní ọgbà ẹ̀wọ̀n ní, ó ṣe é ṣe kí òun náà ní ìpín nínú ikú náà.

Ní ti ilẹ̀ dídà, àwọn méjèèjì ní ọ̀rọ̀ yìí yé. Ká ní Akíntọ̀lá kò tètè kú ni, bóyá à bá tí rí ojú ọ̀rọ̀ náà, ohun tí a mọ̀ ni pé, àwọn alátẹ̀lé Awólọ́wọ̀ pọ̀, wọ́n sì tún ní ẹnu ju àwọn ti Akíntọ̀lá lọ, wọn kò sì fi ojú rere wo Akíntọ̀lá. Tí ó bá jẹ́ òtítọ́ ní wọ́n fi oyè Ààrẹ-ọ̀nà kakanfò ré, kò yẹ kí Akíntọ̀lá jẹ oyè náà nítorí pé èèwọ̀ ni kí ènìyàn dáwọ́lé ohùnkóhun tí a bá ti fi ré nílẹ̀ Yorùbá. Tí a bá sì tún wo bí ẹni tí ó jẹ oyè yìí lẹ́yìn Akíntọ̀lá ṣe kú, a lè fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ wí pé a ti fi oyè Ààrẹ ré, èèwọ̀ sì ni pèlú. Olóyè Abíọ́lá tí ó jẹ oyè yìí lẹ́yìn tí olóògbé Akíntọ̀lá náà kú sínú rògbòdìyàn ọ̀rọ̀ òṣèlú ni.

Èèwọ̀ tí ó tún dàbí ilẹ̀ dídà nínú òṣèlú ilẹ̀ wa ní ti alàgbà Ebenezer Babátọ́pẹ́ (Ebino) àti Alhaji Lateef Jákàndè (Gómìnà ìpínlè Èkó tẹ́lẹ̀ rí) tí wọ́n jẹ́ alátẹ̀lé àti ọmọlẹ́yìn olóyè Awólọ́wọ̀, tí wọ́n gba oyè alákòóso (mínísítà) lọ́wọ́ ìjọba Abacha. Àwọn ọmọ Yorùbá kò fara mọ́ èyí nítorí pé, wọ́n rí ìwà àwọn méjèèjì yìí gẹ́gẹ́ bí ìwà ọ̀dàlẹ̀. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé, wọn kò jà fún ẹ̀tọ́ olóyè Abíọ́lá tí ìjọba Bàbáńgídá fi dùn-ún gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó díje-yege fún ìbò ọjọ́ kejìlá oṣù kẹ́fà ọdún 1993. Wọ́n gbà pé àwọn méjèèjì yìí kò ṣojú ṣẹ̀yìn fún ọmọ ìyá wọn (Abíọ́lá) tí ó wà ní àtìmọ́lé kí wọ́n tó gba oyè lọ́wọ́ Abacha. Èèwọ̀ ní ohun tí wọ́n ṣe yìí, ìyà sì wà fún irú ìwà yìí pẹ̀lú. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé àwọn méjèèjì ní ó ń jẹ ìyà dídẹ́jàá èèwọ̀ lọ́wọ́ lọ́wọ́ báyìí nítorí pé wọn kò rọ́wọ́ mú mọ́ rárá nínú ọ̀rọ̀ òṣèlú ilẹ̀ wa. Alhaji Jákàńdè ni ẹni tí gbogbo ọmọ Yorùbá ti lérò wí pé yóò wọ bàtà tí olóògbé Awólọ́wọ̀ bọ́ sílẹ̀ ṣùgbón àìṣedéédé rẹ̀ yìí ní ó ṣe àkóbá fún un. Ọ̀pọ̀ àwíjàre ní àwọn méjèèjì yìí ti sọ lórí ọ̀rọ̀ yìí tí àwọn ọmọ Yorùbá kò fẹ́ gbọ́.

Ọ̀rọ̀ èèwọ̀ jẹ jáde ní ọdún 1983 nígbà tí ìjọba Ológun ti Bùhárí gbé Olóògbé olóyè Adélakùn (Ẹ̀rù ò bodò) tí ó fìgbà kan jẹ olórí àwọn Jàndùkú fún ẹgbẹ́ Awólọ́wọ̀ (U.P.N) àti Shagari (N.P.N) jù sí àtìmọ́lé ni ìlú Ìbàdàn. Inú àhámọ́ yìí ní ó wà títí tí ẹ̀mí rẹ̀ fi bọ́. Ìgbàgbọ́ àwọn ọmọ Yorùbá tí ó mọ̀ pé akínkanjú àti alágbára èèyàn

nípa tí egbò igi ní ọkùnrin yìí ni pé àhámọ́ tí ó wà fún ìgbà pípé ní ó ṣokùnfà dídá ẹ̀já èèwọ̀ tí ó wọ̀ láti ọjọ́ pípẹ́. Èyí gan-an ní ó fa sábàbí ìkú u rẹ̀ nítorí pé àwọn oògùn tí ó wà lára rẹ̀ tí ó yẹ kí ó ṣe ètùtù wọn ni kò ní òmìnira láti ṣe títí tí ó fi kú.

Èèwọ̀ tún ni kí ènìyàn jalè nínú àṣà àti ìṣe àwọn Yorùbá. Ìgbàgbọ́ wọn ni pé, ẹni tí ó bá jalè ní ó ba ọmọ jẹ́ àti pé ìjìyà pàtàkì wà fún ẹni tí ó bá dá ẹ̀já irú èèwọ̀ bẹ́ẹ̀. Nínú ètò ìṣèjọba ilẹ̀ wa, ọ̀pọ̀ nínú àwọn ọmọ Yorùbá ní ẹ̀rí wà pé wọ́n dẹ́jàá èèwọ̀ yìí tí oníkálùkú wọn sì gba ìdájọ́ ẹsẹ̀ wọn bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ. Lára àwọn ọmọ Yorùbá tí a lè sọ pé ó tún dẹ́jàá èèwọ̀ olè jíjà ní ẹni tí ó ti fìgbà kan jẹ́ ọ̀gá àwọn ọlọ́pàá pátápátá nínú ìjọba àwarawa tí Ọbásanjọ́ ti jẹ ààrẹ apàṣẹ wàá, ni a mọ̀ sí Tàfá Balógun. Àwọn àjọ tó ń rí sí ìwà àjẹbánu àwọn olóṣèlú (EFCC) lábẹ́ àkóso ọ̀gá ọlọ́pàá kan tẹ́lẹ̀ rí, ọ̀gbéni Rìbádù, fi ẹ̀sùn jíjí owó ìlú bí bílíọ́nù mẹ́tàdínlógún Náírà tí ó kó sí oríṣìí ilé ìfowópamọ́ ní orúkọ ara rẹ̀ àti ti àwọn ẹbí rẹ̀. Ó tó ẹ̀sùn márùndínláàdọ́ta (54 count charges) tí wọ́n fi kàn án. Ìyà ẹ̀ṣẹ̀ Tafa Balógun fún dídẹ́jàá èèwọ̀ olè jíjà yìí ni pé, wọ́n kó ṣekeṣeke si ní ọwọ́ ní gbogbo ìgbà tí ó ń jẹ́ ẹjọ́, wọ́n gba ọ̀pọ̀lọpọ̀ dúkìá tí ó ní, wọ́n sì rọ̀ ọ́ lóyè gẹ́gẹ́ bí ọ̀gá àgbà fún gbogbo àwọn ọlọ́pàá ní ọdún 2005. (Daily Independent 2005:2).

Olóṣèlú tí ajere ọ̀rọ̀ olè jíjà tún sí mọ́ lórí ní olóyè Bọ̀dé George tí ó jẹ́ ògbóntarìgì àti alákòóso fún ẹgbẹ́ PDP ní gbogbo ìwọ̀ oòrùn ilẹ̀ Nàìjíríà. Ní ọjọ́ kejìdínlọ́gbọ̀n oṣù kẹwàá ọdún 2009 ní àwọn àjọ EFCC fi ẹ̀sùn kan Bọ̀dé George àti àwọn márùn-ún mìíràn wí pé wọ́n lu àjọ tó ń rí sí ẹrù tí ó ń jáde àti èyí tí ó ń wọlé sí ojú omi (Nigeria Port Authority) ní jìbìtì bílíọ́nù márùndínláàdọ́rún-ún Náírà (N85billion). Gẹ́gẹ́ bí ọmọ ẹgbẹ́ àjọ oní ẹrù ojú omi yìí (Board member), ẹ̀sùn wí pé iṣẹ́ tí wọ́n ti gbé síta fún àwọn agbaṣẹ́ṣe tẹ́lẹ̀ tí wọ́n sì ti gba owó pé lórí rẹ̀ (contract splitting) ní àwọn Bọ̀dé George tún gbé síta bíi ẹ̀ẹ̀mejì sí ẹ̀ẹ̀mẹta tí wọ́n sì tún gba owó rẹ̀ sápò. Ìyà ẹ̀ṣẹ̀ tí Bọ̀dé George fún dídẹ́jàá èèwọ̀ olè jíjà tàbí jìbìtì lílù ní ẹ̀wọ̀n ọdún méjì tí adájọ́ àgbà, Oyèwọlé jù ú sí (the free Encyclopedia).

Ọmọ Yorùbá tí èèwọ̀ olè jíjà ṣéwo mọ́ lórí nínú ètò ìṣèjọba ilẹ̀ wa ni olóògbé Sunday Afọlábí tí ó ti fi ìgbà kan jẹ́ alákòóso fún ọ̀rọ̀ abẹ́le (Minister for Internal Affairs). Ìjọba Ọbásanjọ́ gbé e jù sí àtìmọ́lé ní Dec. 5th 2003 lórí ẹ̀sùn pé ó gba owó ẹ̀yìn tí iye rẹ̀ jẹ́ mílíọ̀nù méjì dọ́là ($2m dollars) lọ́wọ́ ilé iṣẹ́ tí wọ́n gbé iṣẹ́ káàdì ìdánimọ̀ tí orílẹ̀ èdè Nàìjíríà (National Identity Card) fún. Ilẹ̀ Faransé ní àwọn ilé iṣẹ́ náà ti wá 'SAGEM FIRM' sì ní orúkọ wọn. Ikú bo àsírí ní a lè pè ní ìyà ẹ̀sẹ̀ olóògbé náà nítorí pé lórí ọ̀rọ̀ yìí ní ó kú sí ní ìlú Lọ́ńdọ̀ọ̀nù. Èyí ga-an ní ó fà á tí ilé ẹjọ́ fi dá ẹjọ́ náà nù pátápátá. (Daily Independent, June 2004 :9]. A lè sọ pé ìjìyà ẹ̀ṣẹ̀ yìí wá láti ọwọ́ ènìyàn àti Olódùmarè tí ó fi ikú bò ó láṣìírí.

Ajere èèwọ̀ olè jíjà kò ṣàìṣílé orí Ọládiméjì Bánkọ́lé tí ó ti fìgbà kan jẹ́ abẹnugan ilé ìgbìmọ̀ aṣòfin kékeré tí orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ní Àbújá. Lára ẹ̀sùn tí àwọn àjọ tó ń rí sí ìwà àjẹbánu (EFCC) fi kàn-án ni pé ó bu ọwọ́ lu kí bánkì gbé owó kan tí iye rẹ̀ jẹ́ bílíọ̀nù mẹ́wàá Náírà (N10billion) jáde láìsí ẹ̀rí tàbí ìdí pàtàkì fún gbígbé owó náà jáde. Awuyewuye bí bílíọ̀nù méjì-ó-lé-díẹ̀ ṣe pòórá lórí ọ̀rọ̀ a ra mọ́tò a kò ra mọ́tò àti mílíọ̀nù mẹ́sàn-án Náírà tí ó wà fún ètò ìṣúná tí ilé ìgbìmọ̀ aṣòfin ná ní ọdún 2008/2009 gan-an kò ní ìyanjú. Bẹ́ẹ̀ sì ni ọ̀rọ̀ yìí ṣẹ́wo mọ́ Bánkólé lára. (The Punch, June 25, 2011:)

Ohun tí a lè kà gẹ́gẹ́ bí ìjìyà èèwọ̀ olè jíjà yìí ni pé, bí agbára rẹ̀ ṣe tó nínú ètò ìṣèjọba ilẹ̀ Nàìjíríà náà ní ó ṣe ṣẹ̀sín tó. Ìdí ni pé, yàtọ̀ sí pé ó sun inú àhámọ́ àwọn àjọ (EFCC) fún bí ọjó díè, wíwọ́ ni wọ́n ń wọ́ ọ kiri, tipátipá sì ni wọ́n fi gba òmìnira ọjó ráńpẹ́ (Bail) fún-un. Èyí já sí pé kí Ọládiméjì Bánkólé máa ti ilé rẹ̀ wá jẹjọ́. Nígbẹ̀yìn gbẹ́yín, wọ́n da ẹjọ́ náà nù lọ́nà tí kò tẹ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ èèyàn lọ́rùn nítorí pé wọ́n nígbàgbọ́ pé ọwọ́ kan ọwọ́ ní ọ̀nà tí Ìjọba Jonathan tí wọ́n jọ jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ òṣèlú kan náà fi ọ̀rọ̀ náà ṣe. Ṣùgbọ́n a lè sọ pé ìyà ẹ̀ṣẹ̀ Olódùmarè fún Diméjì Bánkọ́lé ni pé láti ọdún 2011 tí ọ̀rọ̀ náà ti ṣẹlẹ̀, ẹnikẹ́ni kò gbọ́ orúkọ rẹ̀ mọ́ lágbo òṣèlú. Èèwò mìíràn tí ó tún wà nínú àsà Yorùbá tí àwọn ọmọ Yorùbá

dẹ́jàá rẹ̀ nínú ìṣèjọba orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ní ìpànìyàn. Èèwọ̀ ni kí ẹnì kan gba ẹ̀mí ọmọlàkejì rẹ̀, ẹni tí ó bá ṣe èyí nínú àṣà Yorùbá, ikú ní ìyà ẹ̀ṣẹ̀. Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé Olódùmarè nìkan gẹ́gẹ́ bí Adẹ́dàá àti Aṣẹ̀dá ní ó ní àsẹ láti gba ẹ̀mí ènìyàn.

Nínú ètò ìṣèjọba ilẹ̀ yìí, òpọ̀lọpò ọmọ Yorùbá ní àwọn ọ̀bàyéjẹ́ ti rán lọ sí ọ̀run pàjáwìrì láìròtẹ́lẹ̀. Lára wọn ní aya Baṣòrun M.K.O Abíọ́lá tí gbogbo ènìyàn díbò yàn gẹ́gẹ́ bí ààrẹ orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ní ọjọ́ kejìlá, oṣù kẹfà ọdún 1993 ṣùgbọ́n tí ìjọba ìgbà náà, lábẹ́ àkóso Ògágun Àgbà Gbàdàmọ́sí Bàbáńgídá fa igi lé ètò ìdìbò náà tí wọ́n sì tipasẹ̀ èyí ju M.K.O sí àtìmọ́lé Nínú làásìgbò yìí náà ní àwọn alágbà-pa Ọ̀gágun Abacha ti yìnbọn pa aya Basọ̀run Abíọ́lá Olóògbé Kúdírátù Abíọ́lá.

Ohun tí a lè rí gẹ́gẹ́ bí ìyà ẹ̀ṣẹ̀ àwọn tí ó ṣiṣẹ́ yìí ni pé, inú ọgbà ẹ̀wọ̀n ní wọn wà láti ọdun 1999 tí Ààrẹ Olúṣẹ́gun Ọbásanjọ́ ti di Ààrẹ títí di Ọgbọ̀njọ́ Oṣu kinni, Ọdún 2012 ti adájọ́ ní kí wọ́n yẹgi fún Al-Mustapha ati Lateef Ṣófọláhàn ti ajere ọ̀rọ̀ náà ṣí mọ́ lórí. Nígbẹ̀yìn, ìpè kan tún wá fún pípe ẹjọ́ kò-tẹ́mi-lọ́run, èyì gan-an ni ó tún ṣokùnfà bí wọ́n ṣe da ẹjọ́ òhún nù, tí wọ́n sì ní kí àwọn ọ̀daràn máa lọ ní àlàáfíà. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé Olódùmarè yóò tún ẹjọ́ náà dá àti pé bí ọba ayé kò bá mú àwọn ọ̀daràn yìí, Ọba Òkè yóò mú wọn. Tíì ìjàngbòn tí ó ní mọ́jèlé nínú ní a gbọ́ pé wọ́n fún Baṣọ̀run Abíọ́lá fúnrarẹ̀ mu tí ó fi gbé ẹ̀mí mì láìmọ ẹni tí ó ṣe iṣẹ́ láabi náà títí dí òní. Ọmọ Yorùbá tí àwọn adẹ́jàá èèwò ìpànìyàn tún pa ní olóògbé onímọ̀-ẹ̀rọ, Fúnṣọ́ Williams. Ọjó kẹtàdínlógbọ̀n, oṣù kéje ọdún 2006 ní àwọn agbanipa wọ ilé rẹ̀ ní Dolphin Estate láti so ó mọ́lẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹran ìso kí wọ́n tó dúmbú rẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìjọba kò ti rí àwọn tí ó ṣiṣẹ́ ibi náà títí di òní, ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ẹlẹ́sẹ̀ kan kì yóò lọ láìjìyà.

Ẹja ńlá ọmọ Yorùbá tí àwọn òbàyéjé tún yọwọ́ kílàńkó rẹ̀ kúrò nínú ibú ètò ìṣèjọba ilẹ̀ Nàìjíríà látàrí dídẹ́jàá èèwọ̀ ìpànìyàn ní olóògbé Bọ́lá Ìgè tí ó ti fi ìgbà kan jẹ Gómìnà ìpínlè Ọ̀yọ́ àti alákòóso (Minister) fún ọ̀rọ̀ iná mọ̀nàmọ́ná àti òfin. Ọjọ́ kẹtàlélógún, oṣù kejìlá ọdún 2001 ni wọ́n pa á sínú ilé rẹ̀ ní Bódìjà

ní ìlú Ìbàdàn. Afurasí pàtàkì tí ó lọ́wọ́ nínú ikú rè ní olóyè Omíṣoore tí a tún dìbò yàn lọ sí ilé ìgbìmọ̀ aṣòfin àgbà ní Àbújá nígbà tí ó wà ní àtìmọ́lé fún ìgbà pípẹ́ lórí ọ̀rọ̀ yìí. Afurasí náà ti gba òmìnira báyìí, ilé ẹjọ́ sì ti dá ẹjọ́ náà nù báyìí, ó sì tún ti gba ipò mìíràn nínú ẹgbẹ́ òṣèlú tuntun tí ó wà báyìí, ṣùgbọ́n ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ẹlẹ́ṣẹ̀ kan kì yóò lọ láìjìyà.

## Ìmújáde Èrò

Láìsí àníàní, oríṣìí èrò ni àlàyé àti atótónu tí a tí ń ṣe bọ̀ mú jáde. Ó hàn gbangba pé èèwọ̀ ni ó di òfin ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá àti pé, ó jẹ́ ọ̀kan lára àṣà àti ìṣe tí a fi ń to ìlú lọ́nà tí kìí fí sí ìwà ìdàlúrú. Èèwọ̀ yìí gan-an náà ni a rí gẹ́gẹ́ bí òfin tàbí ohun tí ofin ilẹ̀ yìí sọ pé kò wọ̀ lóde òní. Lára ìmújáde èrò iṣẹ́ yìí ni pé, dídẹ́jàà èèwọ̀ dúró gẹ́gẹ́ bíi rírú òfin àwùjọ òde òní èyí tí ó jẹ́ pé ìjìyà rẹ̀ yẹ kí ó wá láti ọwọ́ ènìyàn (àwọn ìjọba) gẹ́gẹ́ bí òfin ṣe là á kalẹ̀ àti gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà ní ìbámu pẹ̀lú ìjìyà fún dídẹ́jàá èèwọ̀ ṣùgbọ́n, ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni kìí rí bẹ́ẹ̀ nítorí ọ̀rọ̀ òṣèlú àti àwọn olóṣèlú tí ó máa ń da ọwọ́ rú lórí ètò ìdájọ́ àwùjọ òde òní. Èyí gan-an ni ó jẹ́ kí àwọn ènìyàn nígbàgbọ́ pé ọ̀daràn tó bá dẹ́jàá èèwọ̀ tàbí rú òfin, tí ìjọba kò sì ṣe ìdájọ́ tó tọ́ fún ìgbà pípẹ́, Olódùmarè yóò ṣe ìdájọ́ tó tọ́ àti èyí tí ó yẹ nítorí pé ẹlẹ́ṣẹ̀ kan kì yóò lọ láìjìyà. Ìgbàgbọ́ Yorùbá nínú èèwọ̀ àti dídẹ́jàá èèwọ̀ ni a gbé wọ inú ètò ìdájọ́ òde òní nípa wí pé, ìgbàkúùgbà tí ìjọba bá ti fi ẹjọ́ ọ̀daràn tí àwọn ara ìlú mọ̀ pé ó ní ọwọ́ ìjọba nínú falẹ̀, dájúdájú, Olódùmarè yóò ṣe ìdájọ́ tí ó tọ́ àti èyí tí ó yẹ fún irú ọ̀daràn bẹ́ẹ̀. Tí a bá sì wòó dáadáa, irú ọ̀daràn bẹ́ẹ̀ máa ń kú ikú gbígbóná tàbí kí ohun tí ó fi ọ̀nà ẹ̀bùrú jí tàbí kó jọ paré mọ́ ọn lójú. Tí èyí bá ṣẹlẹ̀, èèwọ̀ tàbí òfin gbèjà ara rẹ̀ nìyẹn.

## Ìkádìí

A ti ná ìgbárá a sì tún ti ná ìgboro lórí àgbéyẹ̀wò èèwọ̀ Yorùbá nínú ètò ìṣèjọba ilẹ̀ Nàìjíríà. A ti yàn nàná oríṣìí ìtumọ̀ tí àwọn onímọ̀ fún èèwọ̀. Bákan náà, ní a ti túṣu dé ìsàlẹ̀ ìkòkò lórí orírun èèwọ̀. A kò salâì tan ìmọ́lẹ̀ sí 'ẹ̀já dídá' àti àwọn ọ̀nà tí ọmọ Yorùbá gbà láti dẹ́jàá àwọn èèwọ̀ kan àti ìjìyà wọn nínú ètò ìṣèjọba ilẹ̀ Nàìjíríà. Gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a ṣe nínú iṣẹ́ yìí, èèwọ̀ jẹ́ ọ̀kan lára

àwọn èròjà òfin láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ àti pé ó wà lára àwọn ohun tí àwọn bàbá ńlá wa ń lò láti fi ṣètò ìlú tí ìlú fi ń rójú ráàyè. Tí a bá wo àwọn òfin inú bíbélì bíi: ìwọ kò gbọ́dọ̀ ṣàgbèrè, ìwọ kò gbọ́dọ̀ jalè, ìwọ kò gbọ́dọ̀ pa ènìyàn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A ó ri pé, ó wà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn èèwọ̀ ilẹ̀ Yorùbá, bẹ́ẹ̀ ní kò sàìṣe rẹ́gí pẹ̀lú òfin ilẹ̀ Nàìjíríà. Fún ìdí èyí, a lè sọ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ òfin ilẹ̀ wa ni ó dúró gẹ́gẹ́ bí èèwọ̀ ilẹ̀ Yorùbá èyí tí ògọ̀ọ̀rọ̀ ọmọ Yorùbá kò ná-án-ní mọ́ báyìí. Èyí gan-an ni ó fà á tí ohun gbogbo kò fi lọ déédé mọ́ ní orílẹ̀ èdè yìí, tí ohun bùrùkù ṣe ń rọ́ lu ohun bùrùkù.

Ohun tí ó tún fojú hàn kedere nínú pépà yìí ni pé, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, ìjìyà wà fún dídẹ́jàá èèwọ̀ tàbí rírú àwọn òfin ìdàjọ́ wa lórílẹ̀ èdè yìí, ọwọ́ tí ìjọba fi mú ìjìyà ìwà ọ̀daràn kò fi bẹ́ẹ̀ dára tó. Ìdí ni pé ìdájọ́ kìí yá lórílẹ̀ èdè yìí àti pé fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún, ẹlòmíràn lè má gba ìdájọ́ ẹ̀ṣẹ̀ ìwà ọ̀daràn títí àwọn ènìyàn yóò fi gbàgbé pátápátá. Èyí gan-an ni kò jẹ́ ḱi àwọn ènìyàn nígbàgbọ́ nínú ètò ìdájọ́ mọ́ nítorí wọ́n rò pé àṣegbé ni ìwà ọ̀daràn tí àwọn kan bá wù lórílẹ̀ èdè yìí. Nípasẹ̀ èyí ni àwọn ènìyàn kò ṣe káàràmáàṣìkí èèwọ̀ mọ́, tí àlàbọrùn ìwà ìbàjẹ́ wá di ẹ̀wù mọ́ wa lọ́wọ. Ìdájọ́ dídẹ́jàá èèwọ̀ kìí pẹ́ láyé àtijọ́, ní yàjóyàjó ni àwọn Òòṣà máa ń ṣe ìdájọ tí ohun gbogbo fi ń lọ létòlétò.

Àìbìkítà àti àìná-án-ní àwọn èèwọ̀ yìí ní ó fà á tí ìwà ajínigbé, agbénipa àti jíju àdó olóró káàkiri ṣe di bárakú nínú ètò ìṣèjọba ilẹ̀ yìí. Ó yẹ kí àwọn ènìyàn orílè èdè yìí, pàápàá jùlọ, àwọn ọmọ Yorùbá mọ̀ pé ‘ìṣẹ̀ṣe làgbà’ àti pé “ná-án-ní, nà-àn-nì, ná-án-ní, ohun tí a bá ní ni à ń ná-án-ní, ọmọ aṣẹ́gi tà ló ń ná-án-ní èpo igi”. Kí ọmọ Yorùbá káárà-máàṣìkí àwọn ohun tó dára tí àwọn baba ńlá wa fi sílẹ̀ fún wa. Ó yẹ kí a mọ̀ wi pé kò sí ibi tí a kìí ti dáná alẹ́, ọbè ni yóò dùn ju ara wọn lọ. Àwọn òyìnbó tí a máa ń se àwòkọ́ṣe wọn kò sàì ní èèwọ̀ tí wọn pẹ̀lú. Èèwọ̀ náà ní ó dúró gẹ́gẹ́ bí òfin tí wọ́n àti pé àwọn kìí rúfin, wọn kìí kọtí ọ̀gbọin sẹ́bọ ni ohun gbogbo ṣe ń lọ déédé lọ́dọ̀ tiwọn. Ó yẹ kí àwa náà padà sí ẹsẹ aárọ̀, kí a jáwọ́ nínú àpọ̀n tí kò yọ̀, kí a lọ gbé omi ilá kaná, kí a bọ̀wọ̀ fún òfin, kí a pa èèwọ̀ mọ́, kí ayé lè dára fún takọ tabo. Ìṣẹ̀ṣe làgbà.

**Ìwé Ìtọ́kasí**


Adeleye, J.O. (2020), Eewo (Taboo) in Yoruba Culture: A philosophical investigation, *AMAMIHE: Journal of Applied Philosophy*, Vol. 18, No 6. Pp. 42 - 48

Adéoyè, (1978) À*sà àti ìse Yorùbá*, Ìbàdàn, Oxford University Press Ltd.

Agoro, O.F. (2021), Analysis of People's opinions on the Significance of Southwestern Nigeria, *Journal of Humanities and Social Science.* Vol. 19, No. 6, pp 173 -186

Ajayi, S.O. (2022), Rejuvenation of Taboo as mechanism for society, *African Journal of Religion Philosophy and Culture* Vol.3, No.2.

Akintan, O.A. & Oyenuga, F.O. (2020), Taboo and Moral Reinforcement in Yoruba Traditional Thought, *Al-Hikmat Journal of Philosophy, Vol. 40, Pp. 1-9*

Oladiran, A.M. (2020), Orò Pípè: Ètùtù Àfẹnuṣe Nínú Ọdún Orò ní Ògbómọ̀ṣọ́, *Ọ̀PÁŃBÀTÀ: LASU Journal of African Studies*, Vol. 10, No. 2, Pp. 61-75.

Ọlájubù, O. (1975) *Ìwé Àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá*, Ìbàdàn, Longman Nigeria Ltd.

Olatunji, S.A. (2021), An Overview of Prohibitions in the Holiness Code and Taboos, *International Journal of Advanced Research in Management and Social Sciences*, Vol. 10, No. 3, Pp. 10-23.

Bolarinwa, A.O. & Ajayeoba, B.B. (2021), Representation of Obaship Institution in Adéọlá Fálẹ́yẹ's Poetry, *Ọ̀PÁŃBÀTÀ: LASU Journal of African Studies*, Vol. 9, No. 1, Pp. 49-66

Ìdòwú, Bólájí (1996) *Olódùmarè God in Yorùbá Belief*, Ìbàdàn, Longman Nigeria.

Mike, O. (2004) *Yoruba Superstitions Belief*, Ìbàdàn, Jones Ltd.

Adéwọyin, (2009) *Ìmọ̀ Èdè, Àṣà, àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá*, Ìbàdàn, WADDS NIG Ltd.

Ọláọba, O. B. (2001) *Sourany Data for the Reconstruction of Yorùbá Legal Tradition*, Ìbàdàn, Canaan Publishing Company.

Odeajo, L. (1997), *Bólá Ìgè: Ọkùnrin Takuntakun*, Ìbàdàn, Newness Quality Printers.

Crystal, D. (1997) *The Encyclopedia of Language*, Cambridge.

Táíwò, J.O. (1986) "*Èèwọ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá" nínú" nínú Yorùbá Gbòde*, vol. 1 & 2, Lagos, Macmillan Nigeria Publishers Ltd.

**Newspapers**

Daily Independence, June, 2024 & 2005

The Punch, June 25, 2001